

*AWOGBA Omode fun Girl, Ert, Hiku - ehin, Orere. Ra Tire NI Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS*



# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



U. T. C.
SERVES
YOU
WELL



VOL. VIII No. 457. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MARCH 3, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)


## ITAN OKE-ODE ILE-IRE F'ARAHAN

Ki aio bẹrẹ ọrọ esi ti mo ti fẹ fi lori akọ irọ ti ko boju fun ẹnikẹni ti arakurin S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ pa sinu irohin Eleti-Ọfẹ ti Ọjọ kọkanlelogun oṣu January, 1956. O yẹ ki nfun ẹnyin ọkawe irohin Oloyinmọmọ yi ni itan iṣẹdalẹ ilu Oke-Ọdẹ Ile-Ire niba Ṣoki.

ITAN OKE-ỌDẸ

Eniti o tẹ ilẹ Oke-Ọdẹ do, Maku ni orukọ rẹ njẹ, iṣẹ ọdẹ agbo'bọn ninu igbo ni iṣẹ rẹ, ilu Maku yi ni nwọn npe ni Igbẹsi, lati ilu Igbẹsi yi ni Maku ti ma nṣe ọdẹ rẹ lọ sinu aginju igbo, asi ma ṣe bi oṣu mẹta tabi jubẹlọ nigbamiran ki o to pada wa sile. Ogboju Ọde to daju ni Maku yi iṣe, nitoripe on nikanṣoṣo pẹlu ibọn rẹ ni ma da ṣe ọdẹ rẹ lọ igbo.

Nigbati O ṣe ọdẹ de ibiti Oke-Ọdẹ wa nisis yi, igbo na jẹ ibugbe awọn ẹranko nla ti nwọn si jẹ ẹranko buburu to jẹ wipe bi ẹdẹ kan ko ba da ararẹ l'oju ko gbọdọ wọ igbo na ayafi bi yio ba kan abuku.

Nibẹ ni Maku gbe bẹrẹ si ṣe ọde ninu igbo na, ti o si npa ẹran lọpọlọpọ, a si ma ṣe atan fi yan awọn ẹran to pa, nigbati awon ẹran na ba gbẹ tan, a ma ko lọ si ilu rẹ Igbẹsi; yio si tun pada wa sinu igbo na.

O ti nṣe b yi titi ki o to kọ ago kekere kan (Ahere) sinu igbo na ti o ngbe fun abo lọwọ ojo, o si nṣe ọdẹ rẹ kiri inu igbo na. On nikanṣoṣo pẹlu ibọn rẹ l'owa sinu igbo yi ko si ẹnikẹni pẹlu rẹ nibẹ.

Nigbati o to ki o pada sile ni Igbẹsi, ti awọn enia rẹ ko ri, awọn enia rẹ wa l'epa rẹ de inu igbo ti o nṣe ọdẹ yi nwọn ba nibẹ, o sọ fun wọn wipe ibiti on gbe wa yi dara pupọ fun iṣẹ on, nitorina ki wọn ma ko ẹran ti on ti pa lọ si ile ni Igbẹsi, wọn si gba gbẹ.

Nigbati awọn enia rẹ ri wipe ibujoko rẹ dara ninu igbo yi, awọn enia bẹrẹ si wa ba ni alejo ni orişirişi ati awọn enia rẹ papa, Maku yi jẹ ọlọyaya ati oninu're enia, o ni ifẹ si ẹnikẹni ati onile ati al'ejo, yio yọmọ wọn gẹgẹbi ẹnipe ẹbi rẹ ni gbogbo wọn,

Gẹgẹbi ẹnyin ọkawe ti mọ wipe nigba lailai, ogun adaja papọju, ti idamu rẹ ma nyọ awọn enia l'ẹnu, ọpọlọpọ ni awọn enia ti o ba iponju de ọdọ rẹ ti o si gba wọn tọwọ-tẹsẹ. On papa si ni ẹru lọpọlọpọ nitori asiko ẹru tita ni igba na. Maku ra ibọn fun awọn aburo rẹ to wa ba nibẹ, awọn si nṣe ọdẹ lọ bakanna.

Bẹ ni Ọgbẹni Maku yi ṣe wa ninu igbo na, ti ibẹ si bẹrẹ si kun fun awọn enia, eyi l'ojẹ ki nwọn sọ orukọ ibẹ ni Oke-Ọdẹ titi di oni yi, Ni gbogbo igbati Maku fi wa ninu igbo yi ni gbogbo ẹniti o ba ti gbọ wipe Ogboju ọdẹ kan wa nibẹ nwa si ọdọ rẹ fun abo lowo ogun igbana.

Maku yi bi ọmọ pupọ mẹwa ni awọn ọmọ bibi inu rẹ, ọkunrin meje (7) obinrin jẹ mẹta (3) nigbati ahere ti Maku kọ yi bẹrẹ si di ilu, o wa fi awọn aburo rẹ jẹ oye bi Balẹ ati awọn ọmọ papa, o nfi wọn jẹ oye to yẹ si Abule' kọkan ti o di ilu loni.

Nigbati ilu yi bẹrẹ si gboro, ti o ni awọn ilu agbegbe ni nwọn ṣe npe ni Oke-ọdẹ Ile-Ire ninu awọn ti Ọgbẹni Maku fi inu rere gba si ilu ti wọn ki iṣe ọmọ bibi inurẹ ti o fi oye ta l'ọrẹ tabi da lọla ni awọn ọmọ wọn fẹ sọ arawọn di onilu. Oke-ọdẹ ni Maku ku si, ile rẹ si ni asinku rẹ si.

Eyi jẹ itan bi ilu Oke-ọdẹ tiṣe ṣẹ. Iyoku di ọsẹ to mbọ l'agbara Ọlọrun

G. A. Maku


THE NATIONAL BANK

Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ oniṣowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la eju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—

The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## OMI TAN LẸHIN ẸJA

Irohin kan wa wipe awọn Ogunna-gbomgbo inu ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) pada lẹhin Ọgbẹni Adegoke Adelabu.

Awọn igi-lẹhin ọgba rẹ na ni a gbọ wipe wọn kọ'we si ọgbẹni Adelabu pe kio yọwọ yọṣẹ kuro ninu Igbimọ ilu Ibadan ki o ma ba orukọ ẹgbẹ jẹ

Bakanna ni awọn tun sọ fun awọn enia,mẹrin yoku ti iwadi Ọgbẹni Nicholson bawi awọn ogunna- gbomgbo na ni Ọgbẹni Babatunji Olowofoyeku, Dr. Okeshukwu Ikejiani Dr. Sanya Ọnabamiro Ọgbẹni S. K. Olumofin, Olu Fakayọde ati Ọgbẹni A. J. Nicholson Sangster.

ABỌ REO !


TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe,
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6d
Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
10A Moloney Bridge St.
LAGOS.


## L. A. F. A. Elects Officers For 1956.



Mr. ALEX. ONI

He was re-elected Chairman of the Lagos Amateur Football Association for this year.

At the annual general meeting of the Lagos Amateur Football Association held at St Georges' Hall, Broad Street, Lagos, on last Thursday, February 23, 1956, Mr. Alex Ola Oni was re-elected Chairman for the year 1956/57.

Other officers of the Association are Messrs: Efiong, E. Okon (Secretary) and J. J Phillips (Treasurer).

## Alaiyeluwa Oba Gesi Soro Iwuri Nipa Nigeria

**Ko si ho ti ri ni irohin ojo ti awon asoju ile Nigeria merer'n lo ba awon ijimi, enia je Apeje nla kan papo ni Guildhall nigboro ilu nla London, eyiti Olola Mayor London pe lati fi ye Oba Elizabeth keji si wipe o k'abo irin ajo re si ile Nigeria o ku ewu ona.**

Ninu apeje ti a nwi yi, die ninu awon gbajumo enia ti o wa nibe lojo na Ogbeni Okorodudu ati iyawo re, Mbu ati iyawo re Commissioner ile Hausa ati ti ile Ibo. Oba paapa ati Oko re, Anthony Eden Prime Minister ilu Oba, Winston Churchill, Hugh Gaitskell Oga awon Alatako ni igbimo, Clement Attlee Sir Lennox Boyd, Iya Oba, ati awon omoba.

Nigbati Mayor ilu London nsoro lo, o wipe, ohun ti o dun mo on ju ni wipe Olola kabiyesi Oba na lo be University College wo ni Ibadan, nitoripe University Ibadan je iyekan pelu ti London. Ile ibiti a gbe nko eko iwosan nibe se ndi ohun ti gbogbo enia nfojusi nisisiyi. Sugbon loni gbogbo awon ara ilu London tonile-talejo mba o yo Kabiyesi fun dide ti o de si ilu yi ni alafia.

Nihin ni Oba Obinrin na dide, ti o si tenu boro, o wipe on pelu Oko on, ko ni gbagbe awon nkan ti nwon fi oju ri tan nile Nigeria. On si nireti wipe ile Nigeria yio je alabasepo pelu wa, nwon o si fi gbogbo agbara won ba wa lopo Ki enia fo aragbabu okun yanrin Sahara soda tabi ki enia fo odi Kano koja si ilu Oyinbo loru ojo kan je ohun iyanu gidi-gidi.

Loju temi, ibukun Olorun lo je. Owe Yoruba ti oba pa ni wipe eniti o ti rin irin ajo lo si ile aiye ti o si ti ri orisi-risi nkan sanse eniti ko de ibi kan. Oba na so wip ile Nigeria yo s'afani nijomiran, awon enia inu re papaa si nte siwaju, mo nireti pe isokan yio s'anfani fun ile Nigeria Oju on yio si ma wa lara awon ara ile na nigba gbogbo, ki Olorun fun Nigeria ni ayo ati alafia.

## (Owe Yoruba)

**Bi ile ba ngbe Osika, ti ko gbe Olotito, bi o ba pe titi ore a su'ni se**


## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

**MEDICINE STORES**

7. Egerton Road, Lagos.




CHARLES ATI ANNE

Aworan inu iwe wa yi niti awon Omo Alaiyeluwa Oba Obinrin ilu Gesi ti o rin irin ajo ibewo wa silu wa Nigeria yi, ati ololajulo oko re Duke of Edinbourgh.

Enyin okawe wa, kini ion awon Omola nwonyi yio ti dun to, nigbati iya won olufejulo ati baba won pada de silu won ni alafia lehin ifojusona fun odidi ojo mokandinlogun, ko si eniti o le so bi ayo okan won yio ti po to.

A ki awon omoba na, Charles (Oba lola) ati Anne, ni iki ayo wipe, e ku afojuba o.

## Ojukokoro Ko Ye Omo Enia

Ni igba laelae, Ijapa ni ore kan on ati ore yi si feran ara won rekoja ala. Ijapa a ma lo si ile ore yi ni Igbagbogbo, ore yi na a si ma wa si ile Ijapa, ohunkohun ti nwon ba ba ni ile ara won a jo je ni.

Ni ojó kan, Ijapa lo si ile ore re yi, o ba Iyawo ore yi nibiti o ti nse ébe, bi Ijapa ti de, o ki daradara, ni ore yi ba lo si inu iyara re lehin Igbati o ti ki Ijapa tan. Nigbati Ijapa joko tan, Iyawo ore re yi lo sinu iyara lati lo mu awo ti yio fi bu onje fun Ijapa. Sugbon ki Obinrin ati oko re to de Ijapa ti lo si idi ikoko ebe, o ho ebe sinu fila ni ireti wipe bi on ba de ile on, on yio je. Laifa oro gun lo titi ki Iyawo yi ati oko re to de Ijapa ti de ebé mo ori o ti joko.

Bi nwon ti de ni Ijapa si wipe on nfe lo si ile on, Inu bi ore re yi, o ni, se bi o wa ki on ni, Ijapa ni on nlo, bo nwon ti nsoro yi beni ebe ti o de mo ori njo o. Ni Iyawo ore yi ba bu ebe si inu awo o ni bi Ijapa ko ba je ko ni lo "Alabonrun d'ewu" ti ori njo Ijapa nwon tun gbe omiran fun nigbati o pe titi ti ebe yi ti njo Ijapa ti ara re ko gba mó ni o bere si tun fila re se bi o ti nse eleyi ni o tun nje éyiti Iyawo yi gbe fun, ibiti o ti nyi fila re sihin-sohun fila re si, ki fila na to si, awo ori Ijapa ti bo mo ebe.

Nigbati fila si tan ti nwon wo inu fila yi, kiki ebe ni, inu bi Iyawo yi ati oko re fun iru iwa ole ti Ijapa hu yi, awon mejeji ba ko igi bo Ijapa, ni nwon ba le Ijapa kuro ni ile won, lati igbayi ni ore yi ko ti lo si ile Ijapa mo, ti Ijapa na ko si wa si ile ore yi mo, nitori na mo be enyin ekawe, e jeki a so ra fun ojukokoro ojukokoro ko ye omo Enia o.

Iba oro mi re o, Olotu, Ese o

**Eleti-Ofe kun fun irohin to gbadun, gegebi aiye ti nlo, o si nko ni l'ogbon ni pataki.**


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**

*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 28, Kosoko Street, Lagos. P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS — "ELETI - OFE LAGOS" Phone 23370

VOL VIII. NO. 457,   LAGOS, SATURDAY   MAR. 3, 1956.


## Eyi Se Kelebo O!

Ofin afikun owo-ibode ti Ijọba wa gbe s'ode l'ẹnu ọjọ mẹta yi jẹ ohun to fa ariwo jade ti tonile talejo nke wipe eyi ma ṣe kelebọ o. Ti owo ibode l'ori awọn ọja to nti ilu o'ere wa, ni ari ti a nwi lọwọ, ọrọ na wa di owe Yoruba to sọ bayi wipe:-

"Imu iyale ni a ri ti a nwi
aṣe ẹgbẹrun enia ni o nru ti iyawo bọ lẹhin"

Ninu i'e Igbimọ nla ti ilu Eko (House of Representative) ti nwọn ṣe ni ọjọ Satide ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu February, 1956. Ni ọlọla Gomina agba ti sọ nigbati o gori Halefa ọla rẹ wipe Ijọba yio tun fi kun owo-ori nitoripe owo girimọyan ni ao ni lati lo fun iṣẹ ilọsiwaju ilẹ Nigeria ati lati tun ilu Eko ṣe gẹgẹbi eto ti awọn Olotu Ijọba gbogbo ti ṣe silẹ fun lilo titi di ọdun 1960. Apapọ owo ti ao si lo na nlọ si nkan bi ẹdẹgbẹta-le-lẹgbaji ọkẹ pọnun £91. million).

Rogbodiyan aibalẹ ọkan ti i afikun owo-omi ti awọn Igbimọ ilu Lagos Town Council ṣe nipa owo ti Ijọba tun bu s'ori ile, ni gbogbo enia mbayi lọwọ, eyi ti Ijọba tun gbe jade yi jẹ ohun ti o pa'na ti o si pa orun mọ ẹnikẹni l'ẹnu.

L'ododo ni a nfẹ ilọsiwaju nilẹ wa gbogbo, ṣugbọn ki iṣe wipe ki a fi inira pa gbogbo ara ilu l'ori nipa owo-ode sisan lati fi sọ ilu d'ọtun ni giri-modimu. Iba dara pupọ bi a ba le ma ṣe atunṣe na diẹdiẹ ti ko nisi afikun owo nisisan fun awọn enia ni asiko ti ọkakara wọ'le okokoro yi.

Ni asiko kan ri, ṣaṣa enia ni ẹniti ko le jẹun larin awo, tabi ti ko le "dabira" nipa wipe ki oluwarẹ w'ọle jade nipa ohunkohun ti o ba kan ni ṣiṣe; ṣugbọn l'oni yi nkọ? kilari? ko ha di ki ati jẹun di ijọgbọn ti o sọ ẹlomiran di aya'jule jẹun mọbi-ọbẹ-gbedun.

Nigb ti sanmọri enia ji ti ko ba ẹgbaa ji, ti a tun ni ki o wa san asanle owo fun Ijọba nitori ati tun ilu ṣe, o yẹ ki awọn alaṣẹ ro ti mẹkunnu enia mọ ti arawọn, t awọu ti ko nṣe iṣẹ oṣu l'abẹ Ijọba tabi labẹ awọn Oyinbo Oniṣowo, ti awọn enia bẹ si lọpọ awọn oniṣẹ oṣu si mẹta.

Eyi ṣe kelebọ o!


## VOMICURE




A very Reliable Remedy For Vomiting During Pregnancy Loss Of Apetite Pains Below the Abdomen and All Other Ailments that Make Pregnancy Uncomfortable. No Prescription Needed. Just Buy a Bottle and Enjoy Good Health.

Obtainable from:-
EJIWUNMI MED. STORES LAGOS
and Many other Medicine Stores.


## Ibere Oro

Olotu

Jọwọ gba mi laye ninu iwe rẹ Oloyinmọmọ lati bere ọrọ yi lọwọ awọn ọkawe Irohin Eleti-Ofẹ ki ẹniti o ba ni imọ ki o la ye mi

Tani ẹniti o ni agbara julọ ninu awọn ọrẹ meji? Ina ati Omi. Ni ọjọ kan awọn ọrẹ mejeji yi lọ si ọdọ ọrẹ wọn kan ti orukọ rẹ njẹ Eṣu. Eṣu si fẹ mọ tani yio gba adiẹ ni ọwọ on, Omi dahun o ni emi ni ẹgbọn, nitorina, emi ni yio gba adiẹ na. Ina dahun o ni emi ni o yẹ ki ngba adiẹ na nitori emi ni agba

Wọn bẹrẹ si fa ọrọ yi o fẹ dija d'epo ti wọn fi nbu ara wọn bayi pe, Iwọ alaini anfani l'ara yi, Omi dahun oni bi emi ko ti ni, ni iwọ na ko ni. Bẹ awọn mejeji l'oni anfani ti nwọn nṣe fun araiye.

A fẹ mọ ẹgbọn ati aburo ninu awọn abami ẹda mejeji yi

G. A. Adeniyi
(alias Guinea Boy)

## Iye Awon Omo Ti A Bi

Ni ibẹrẹ oṣu Feb nigbati ọba obinrin ilu Gẹsi fi mbẹ larin wa nibin ọsẹ kini ti ọba na de ni a bi ọdunrun ọmọ (300) lọsẹ kan iye enia ti o fi aiye silẹ nigbana jẹ mejile-lọgọrin.

Lọsẹ keji ti o de iye ọmọ ti a bi jẹ Okoo-leru gbadinmẹta (217) adọrin enia lo fi ile aiye silẹ


## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

IKORODU TRADING COMPANY

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD, IBADAN



## Ipade Igbimo Nla

### ỌRỌ ỌLỌLA GOMINA AGBA

Nigbati Ọlọla Gomina agba ti Ilu Eko Sir James Roberson bọ sori Halefa rẹ ninu ajọ igbimọ nla ti Eko (House of Representatives) o sọ wipe degbẹta le lẹgbaji ọkẹ poun ni Ijọba ilu ko nfẹ na (£91,000,000) lati fi wa ilọsiwaju ati lati fi tun ilu Eko ṣe lati ibẹrẹ ọdun ti awa yi si ọdun 1960 Idaji owo yi, so fi ṣe atunṣe orişirişi ẹrọ isọro nigbati o sọrọ yi tan, ariwo atẹwọ so ku ninu igbimọ na.

Lẹhin ti o pari ọrọ yi tan o tun sọ wipe nipa ominira ti a fẹ lọ gba lọdun yi nilu Oyinbo on nireti wipe awọn ti yio aşayan awọn Igbimọ lọ si ipade na, awọn yio farabalẹ yan awọn ti o lọgbọn lori ti o si ni lakaye lọ si ipada na, ariwo atẹwọ tun sọ nigbti o sọ wipe awọn ti yio ipilẹ isọkan ilẹ Nigeria l'ẹlẹ ti yio si duro şinşin

Sir James tun se alaye siwa ju wipo işẹ ti a fẹ fi girimọyan ti a daruko yi şe ni wipe, a nfẹ ki işẹ Post Office ati gbogbo inu inu rẹ tun bọ gboro si a si nfẹ agbara nla fun awọn Ijọba agbegbe Iwọ orun, Ila orun, Ariwa ati Kamarun, A si nfẹ ki ibusọkalẹ t'ọkọ Ofurufu ti Kano ati ti ilu Eko gboro siwaju ki o si da ajo bi o ti wa, A nfẹ kọ awọn enia dudu ni işẹ gẹgẹbi a ti nwa ọkọ ofurufu şe ati bi a ti şe ntun ọkọ ofurufu şe a nfe tun ebute ọkọ Oy nbo ti ilu Portharcourt şe a nfẹ tun rinọkọ Reluwe rẹ lati ilu Portharcourt lo si Enugu a nfẹ tun awọn oju ọna moto tẹ, a si nfẹ tunişe şe.

Nigbati o ba di ni ibẹrẹ ọdun 1957 a o bẹrẹ ọkọ ọlọfẹ ninu awọn ilowe ti o ba dara, ti ogiri rẹ silẹ polu, A n nfẹ N:B.C. tilẹ wa nihin, a si ni ọmọ ogun oju omi tilẹ Nigeria. a si fẹ ni Ọgagun ti ilẹ enia dudu. Ijọba ngb'ero lati da aye kan silẹ fun ọkan ti yio ma bojuto ilọsiwaju enia dudu o'nu işẹ oba ati ti enişowo. Ọrọ pọ ti Gomina agba sọ Sugbọn aye ko si tobẹ lati gba gbogbo rẹ. Nigbati o pari ọrọ tan, ariwo tun sọ goe!

Sir James fagbo sebẹ Oyinmọmọ ara Eko gba ko iọwo oyinmọmọ.

## Eiye Agbigbo di eiye Oba Obinrin

Lasiko ti ọba Obinrin ilu Gẹsi wa ilẹ Nigeria, nigbati ọba na rin ilẹ de Oke-Ọya, ọkan ninu awọn ohun ti nwọn fi ta a lọrẹ ni Ẹiyẹ Agbigbo kan Ẹiyẹ na ni agogo lẹnu gẹgẹbi ti ẹiyẹ Atiala tabi Atioro, o si ru ẹru sori, eyi ti o jẹki awọn yoruba fi nfi ẹiyẹ na kọrin bayi wipe "Agbigbo, o ku ẹru, ori" O ni jọbọ lọna ọfun rẹ gẹgẹbi ti adiẹ Akukọ ti tobi rẹ to ẹiyẹ Tolotolo.

Idi rẹ ti o fi di ẹiyẹ ọba ni wipo, awọn, ẹgbẹ Ologun ti Kaduna ti a npe ni ede oyinbo bayi wipe "1st Battalion" ti sọ aworan ẹiye agbigbo yi di ami tabi apẹrẹ lati fi mọ ẹgbẹ jagun-jagun yi sọtọ.

Nibiti o ba gbe ri orukọ Queen own Nigeria Regiment, iwọ yio si ri ami ẹiyẹ Agbigbo dipo igi ọpẹ ti nwọ ti nlo tẹlẹ ri.

## Awon Alejo Nla Miran Tun De

Ọdun 1956 ti a wa yi, Odustan tabi Ọdun-itan ni ao ma pee, ti a ko si ni gbagbe titi lailai. Awọn ohun miran ti o tun mbọ wa şẹlẹ ninu ọdun na, akoiti ni mimọ rẹ. Ọdun itan nla lo yẹ ki a ma pe e.

Nitori pe ko pẹ yi ti ọdun na fi bẹrẹ awọn, ohun nlala ni a si bẹrẹ si ri ti o nşẹlẹ ninu rẹ.
(1) Ninu ohun ti a ko riri ti o şẹlẹ ni ti Ọba Obinrin ilu Oyinbo to wa silẹ Nigeria.
(2) Ẹniti Gẹsi yio ba başẹ ọrẹ nwọn o fun ni Ọpa Adehun lati fi şe ami ọrẹ larin ijọba Gesi ati Oluwa re. Gere ti Ọba Oyinbo lọ tan ni awọn ijmi enia ninu awọn Oyinbo Gesi tunde, pelu opa adehun lọwọ, wọn fun igbimọ nla ti Nigeria (House of Representative, Lagos.)

Eyiyi ni adehun wipo, ohun ti Igbimọ ilẹ Nigeria ba de nihin awọn de e lọhun ti o ba jẹ lọna ti ododo bakanna, ni ohun ti Gẹsi ba de lọna otitọ nwọn doe nihin.

## Ibukun Ni Iranti Olododo

Baba Wa Ọwọn
SUNMỌNU MAJẸNRAHUN
(Alias Baba Onigari)

Ẹniti o lọ jẹ'pe Allah, Ọba Ọga Ogo, ni Ọjọ kẹdọgbọn oşu February, ti ọdun 1939.

Lati ọdun Kẹdogun ti o ti fi wa silẹ lọ, bi ana ni o ri l'oju awa ọmọ rẹ.

SUNRE L'AGBALA
OLODUMARE

A. Majẹnrahun
S.A. Majẹnrahun
Salimọtu Majẹnrahnn
Saratu Majẹnrahun


## Western Region Production Development Board

### STENOGRAPHER GRADE 1

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Stenographer Grade I.

Cadidates should possess the Royal Society of Arts Certificate in Shorthand for 100 words a minute and must be able to type at the rate of at least 40 words per minute. A good command of English is essential.

Salary will be in the scale £354 x 18 - 426; £448 x 24 - 520 per annum, point of entry depending on qualification and experience.

Applications, accompained by relevant copies of Certificates/Testimonials, should be forwarded to reach:

The Personnel Secretary,
Western Region Production
Development Board,
Ibadan.

not later than the 7th of March, 1956. Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

YOUR
ENGINE
MAY BE MORE
POWERFUL
THAN YOU THINK!

I.C.A. UNLOCKS ALL THE
POWER IN YOUR ENGINE.

Only SHELL has I.C.A.

IGNITION CONTROL ADDITIVE
(incorporating tricresyl phosphate)

THE MOST POWERFUL MOTOR SPIRIT YOU CAN BUY

## Irora Orikerike

Boya Kidinrin le fa a

Ise Kidinrin ni lati mu awon idoti ti o mbe ninu eje ara kuro nigbati ko ba sise dara-dara idoti na awojo po sibikan, eyi lo njeki awon orike bere si dun ni.

Ohun ti a le fi wosan ni wipe ka se iranlowo fun Kidinrin na ki o le sise rere. Egbogi De Witts na kakiri aiye ni a si nta egbogi na a Opo niau iwe ni a ti ri gba lati odo orisirisi enia ti awon nso iru ise ti De Witts se fun awon Danwo lora okan ni sobu egbogi.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo o ra ni sobu egbogi.

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles



## Enjoy Your Own —Songs—

Songs By Your Own People in the way you love masterly rendering of additional AFRICAN MUSIC :- yours, on obtainable from is



## The Association Of Nigeria Gramophone Dealers . . . :

THROUGHOUT . . . . . .
. . . . NIGERIA . . .


## Awon Olopa F'ole Ole

ILESHA—Laipe yi ni irohin kan wa wipe awon olopa ibile ri ibuba awon oso'le olosa ni ilu kan ti a npe ni Iregun nitosi ilu Ilesha, a gbo wipe opolopo eru eleru ti awon ole ti ri ko ati nkan ti awon ti nfo-le ni won ri ko nibe.

A gbo wipe awon enia bi ogun(20) ni owo awon o'lopa te, obinrin papa tile wa ninu won pelu onise-oru kan (Night watchman).

Ti ilu Onisha ti a gbo tile bu-aya-olegongo, awon ole olosa wonyi le iwe ikede kakiri opopo-ona, lati fi se ikilo fun awon enia wipe awon ti tun bere ise buburu won Ayaworan kan (Photographer) ti oruko re nje Rex. G.C, Anyaoka ni owo awon eruku na te ni Ibudo Moto ni Ochanja, gbogbo eru ni won ji gbe lo.

Ninu ose kanna, nigbati nwon ko ri aye se ise buburu won, ina ni won ki bo Moto ayokele ti oluko ile eko giga titun ti Bethel. (Bethel College) titun Ogbeni Nzegwu.

Ni Ona Ibadan si Ijebu wa Eko, (Ijebu Road) awon ole da Moto nla akeru kan duro, nwon si pase wipe ki awon ero to wo Moto na yara ma ko nkan inu apo won wa. Lehinna won bere si ko apo Koko to wa ninu oko na jade.

Sugbon owo Olorun te won nibe, nitoripe awon Olopa-inu mbo ninu awon ero to woko na, won ra won mu die ninu awon janduku enia na sa wo igbo sugbon owo te enia merin ninu won, nwon si ti fi won sun esun si Kotu.

Gegebi irohin ti o de owo wa kakiri ilu Oke ati ile awon Ibo, iyonu awon ole wonyi ma se npoju nisisiyi, nitorina, a be awon O'lopa Oba, awon Kinlun amunimuye ki won jowo ba ni mojuto awon Onijamba wonyi o.

## Oku Adeja Fo S'ori Omi

IBADAN—Okunrin kan bi omo odun mejidinlogbon ni a gbo wipe o fi ile sile lo se ode eja ninu odo Eleiyele nilu Ibadan ni arin osu yi ni won ri oku re to fo lori omi odo Eleiyele na ni ojo keta to ti lo.

Nigbati nwon ri oku na ni won gbe lo si ile ayewo awon oku (Mortuary) fun Ayewo. Nwon ni oko re l'o sejude omi nigbati o nse ode eja Ganiyu Adedapo ni oruko adeja na nje, agbare-gbabo Oluwadi iku re (Corona) so wipe odo to ri si ni o se iku pa.

## Obinrin kan pade Agbako

A gbo irohin wipe, obinrin Hausa kan ti a npe ni Yeluwa ji ni owuro ojo kan, o wi fun oko re wipe gbogbo ara lo ndun on fun ise ti on se lana.

Sugbon oko re tako, o wipe iro lo npa, ko fe ise lati se ni. O pase fun iyawo re Yeluwa pe ki o lo toju isu fun on l'oko.

Lilo ti obinrin, n lo o lo se agbako awon kokoro Oyin, nwon suru lo nwon si ta a ni ita-kuta, to be ti nwon ni lati gbe lo sile Alaisan.

Awon ijoba lo sibi awon Oyin na wa, iwo si pa won re nwon ko Oyin won wa fun Yeluwa, o si fi won mu eko.


## Awon Dokita Fi Han Wipe

### Ose Palmolive Le Jeki Ara Re Dan Ki o si Jolo Larin Ojo Merinla



**Ara Mi Dan, O Si Jolo Nitoripe**

**Mo Tele Ilana Ti Awon Dokita Se**

*Iba Ohun Ti Iwo Yio Se Niyi:-*
*1. Fi Ose Palmolive we Oju re*
*2. Fi Kiko re pa Oju re, Fun Iseju Kan*
*3. Fi Aso nu kuro. Se be nigba Meta l'ojumo fun Ojo Merinla*




EPO ILE AFIRIKA NI A FI SE OSE YI.

GOLCATE PALMOLIVE L'OSE

## Oba Obinrin nfe gba isimi ojo die



QUEEN ELIZABETH II

Irohin ti gbojikan kakiri wipe, idirę ti oba Obinrin şe ni lati gbatęgun lo si apa ona okun Mediterranean ni wipe, o wahala pupoju lasiko ti o fi wa silę Nigeria. Iro funfun ni eyi ję.

Nitoto ni bosihin-bosohun po fun Oba, şugbon ninu igboke-gbodo rę, ko şe e ni airoju kan. Bi aşa awon Oyinbo, bi enia ba şişę pupo kan, o ni lati gba isinmi, eyi yi ni idi rę ti Oba na şe nfę gba atęgun lo si apa ona okun Mediterrenean,



DUKE OF EDINGBURGH

Duke of Edinburgh ti o nşe oko oba yi yio gba atęgun na ninu Ola nla rę, yio fi oko Ogun ti a npe ni Britania se faaji lo fun oşę kan yio lo ba Oba Obinrin nilu Corsica lehin ire edaraya pelu oko ogun ajumoşepo awon mejeji y'o si ba oko ofurufuru pada sile ki o to to ojo kejidinlogun oşu yi.

A gbo wipe Oba na koiti simi latigba ti o ti pada de irin ajo rę silę Nigeria.

Gbogbo işe ile ti awon ti npati de ni o nyanju ti o si şe won gęgębi o ti to ati bi o ti yę.

Isinmi dara lehin işę

## Ejo Owa Ilesha Nilu Ibadan

IBADAN—A gbo irohin kan wipe okunrin kan ti o nşowo Koko ti o si lowo lowo pe Alaiyeluwa oba Ilesha lejo ędegbeta poun

Bi a ti gbo wipe oro na lo ni wipe nigbati aye ipo oloye Lejoka şi silę okunrin na so wipe, oba to on wa funra rę lati wa gba ędegbeta Poun ki o ba le fi on joye Lejoka na.

Ni ojo Tuesday ti işe ojo dinlogbon oşu February, 1956, ni Kotu nla ilu Ibadan gbo riro ejo na a koi ti gbo idajo o.

---

Ę NI OMO SIN L'OBIMO AWĘ- OYO: Ni ojo kęwa oşu kini odun yi (10.-1. 56) ni Iya wa, Iyafin Ayantoki Ayorinde, Iyawo baba wa Ogbeni Ayorinde ti oruko apele rę gęgębi babalawo nję "ASAPA," fi ile aiye silę lati lo simi ninu ile isimi rę aiyeraiye.

Gbara ti iya onimu're yi ti dakę ni awon omo-oku ti bęrę inawo oku sisin ti iya won owon. Bi won ti nse, bęni won nso, ibon ndun bi igbati ara nsan. Onję ajęti, oti bi ęmu oti oka, bia, ati awon oti miran, a mu yira.

Awon enia pataki-pataki lati Oyo, Awę ati ibomiran ko fi odo awon omo-oku silę. Oruko ile oko Iya wa na ni Ile Fokutu, Awę.

A ki awon omo-oku, papa julo Ogbeni Emmanuel Faębile Ayonrinde ti işę Aręmokunrin Iya wa na pe, o k uawo, ikę ati inawo ti ti iya .







Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P.O. Box 467 Lagos Phone 22870